ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 328 LAGOS SATURDAY JULY 14, — JULY 20, 1962. KỌBỌ MEJI (2D)

# Odomokunrin Kan

## Jabo Lori Petesi Medogbon

### O KU BAMU-BAMU

Anu abiyamọ ṣe gbogbo awọn enia ti nwọn ri oku ọdọmọde kapinta kan ti orukọ rẹ njẹ Rarasaki Ayọdele, ẹni ọgbọn ọdun, nigbati o jalulẹ lori ile pẹtẹsi alakọle mẹdọgbọn ti nwọn ṣẹṣẹ nkọ ni ọdan l'Eko ni owurọ ijẹta ọjọ Alamisi.

Onirohin Eleti-Ọfẹ ni ni ownrọ ọjọ ti ijamba yi ṣe ọkunrin na, o ji, o ni ki iyawo on tuntun ti o ṣẹṣẹ gbe niwọn nkan bi oṣu keji se onjẹ ti o dara silẹ fun o. Bi o ti de ibi iṣẹ o gun oke ile tuntun ti nwọn nkọ na lọ lati lọ mu irin-iṣẹ rẹ kan ti o fi si oke kẹdọgbọn, bi o ti npada bọ ni ẹsẹ rẹ yọ ti o bẹrẹsi yi bọ wa silẹ; ki o to de ilẹ gbogbo agbari rẹ ti fọ, ara on paapa ti pin yẹlẹ-yẹlẹ.

Nigbatii nwọn de ọdọ iyawo rẹ ni ile ti nwọn ngbe ni 17 Cole Street ni Mushin nwọn ba iyawo rẹ nibit o ti npalẹmọ lati se onjẹ ti ọkọ rẹ yio jẹ bi o ba ti ibi iṣẹ de. Ẹnu ya lati gbọ wipe ọkọ rẹ ti jabọ, o si ku lori ile pẹtẹsi OMINIRA alakọle mẹdọgbọn ti Ijọba nkọ l'Ọdan ni Eko.

Awọn ti nwọn jọ nṣe iṣẹ ti ṣa egun oku rẹ ti o fọnka silẹ kaklri fun sinsin.

---

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS,

LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell

Telephone London Wall 4303
Cable & Telegrams Natbaniger ; London
Head Office Representative in London.
E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG

## Baba Onimato So Omo Kan Di Odi Ni Yaba

YABA— Ẹnu ya awọn ọlọpa Yaba nigbati ọmọ ile-iwe kekere kan, Abiọdun Ahmed ẹni dun mẹrindinlogun, sọ fun awọn ọlọpa na ni tesan wọn bi on ti ṣe di odi ti on ko le sọrọ rara mọ.

Ọmọdebinrin na ni bi on ti nti ile-iwe bọ ni on pade ọkunrin onimọto ayọkẹlẹ kan ti o ni ki on wọ'le on a ṣe anu, on a gbe on de ile. Bi awọn si ti de ibi kan, ọkunrin na si lo egbogi kan fun on, on ko si gbọ ọrọ, on ko si tun sọ ọrọ mọ.

Iwe kan ni awọn ọlọpa mu fun ọmọdebinrin na ti o kọ gbogbo ọrọ yi si ki awọn obi rẹ to wa mu lọ si Agbo'le Alawọ ni Oke Arin l'Eko.

---

**LAGOS RACE CLUB**

Last day of June Race Meeting

TODAY

First Race at 3 p.m.

**Come One Come All.**

Hon. Secretary,
Lagos Race Club.

# Irin Ajo Yi Fa Kiki



Eyi ni aworan awọn ọdọmọde Gẹsi meji ti orukọ wọn njẹ Michael Thrust, ọmọ ogun ọdun, ati Anthony Astell, ẹni ọdun mẹrinlelogun nibiti nwọn gbe nfalẹmọ ẹru wọn ni ilu Kent sinnu mọto ti nwọn npe ni Land-Rover Dormobile Caravan ti nwọn fẹ fi rin irin-ajo yi agbaiye ka fun ọdun kan ati abọ. Nwọn ni bi awọn ba ti nlọ ni awọn yio ma gba aworan ilu ti awọn ba de lati le fi wọn ranu ... eyiti nṣe Anthony ti o wa ni apa ọtun ninu aworan yi fẹ kọ. Alọ a dara, abọ a sunan.

---

## Oloye Akintola Ko Yaro

# Iro Ni Nwon Pa

OLOKEMEJI—Laipe yi ni awọn enia kan ntan irohin kakiri wipe Oloye Samuel Ladoke Akintọla, ẹniti o fi igba kan ṣe Olori Ijoba Ipinle Iwo Orun, ti o si wa ni ihamọ ninu igbo Olokemeji nisisiyi, o ti yarọ awọn ọwọ rẹ ati ẹsẹ rẹ si ti rọ bi ewe.

Nigbati a wa di ire na, a ri wipe ko si otitọ kan nibẹ, nigbati onirohin wa kan de ọdọ rẹ ọpọn-ayo ni nwọn ba ni iwaju rẹ lẹhin ti o fi itan ọya jẹ iyan tan. Ko pẹ ti akọwe onirohin wa na de ọdọ Oloye Akintọla ni awọn alejo miran, awọn bi Oloye F. O. Awosika, alaga Igbimọ Itọju-aje fun Ipinlẹ Iwọ Orun (Western Nigeria Marketing Board) wa sọdọ rẹ lati Ibadan, on na si ba awọn alejo yi rin kakiri inu ọgba ki nwọn to pada si ile wọn ni irọlẹ ọjọ na.

A w ọ n oniwe irohin kan ni nwọn ṣe ẹnuforo laipẹ yi wipe a w ọ n gbọ wipe nwọn ti de Oloye Akintọla ni ẹwọn-ondẹ lẹsẹ ati lọwọ ati pe idi lo fi nwọ bi arọ; nwọn ni Oloye Ayọ Roṣiji paapa ti wọ were, o si ngbo bi a j a, tobẹgẹ ti nwọn fi di lọwọ di lẹsẹ, ti nwọn gbee gba ọgba-were l ọ n i A r o l'Abẹokuta.

Irọ ni, Roṣiji wa ni apapa ni ahamọ apapandodo.

**Ki E Foju Sona Fun Irohin Aladun Ninu Ayiluka**

# Awo Irawo

## Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20)

Maṣe fi ẹnu ba enikẹni jẹ; ... y... a dara pupọ fun ọ ti o ba dawọ le nkan bi owo lati ṣe.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Fi ...

aba tabi ipinnu rẹ si igbaman... ki o si sọ ọrọ ẹnu rẹ daradara k... o ba mọ si ọrọ sọ.

ARIES (Mar 21-April 20) Maṣe

ba ẹnikan gbo'nu. Ti o ba ... ẹniti yio ran ẹ lọwọ, iṣẹ ti o nṣe a tọna daradara.

TAURUS (April 21-May 20)

Ẹnikan yio fẹ iranlọwọ lati ... rẹ, o ni lati ṣe suru fun ọpọlọpọ iwọsi ti wa ri lọsẹ yi.

GEMINI (May 21-June 21) Maṣe

bẹru, gbogbo nkan ti o ba fẹ ... yẹ ki o jẹki ọkan rẹ wa nibe lọsẹ yi.

CANCER (Jun 22-July 23) Maṣe

na owo aburadi kan ninu ọsẹ y... nitoripe inawo miran a yọ ... ni alairotẹlẹ. Ṣe ọkan rẹ gin k... o si ma wo ni tirẹ.

LEO (July 24-Aug 22) Ṣọra pupọ

ma ba awọn obinrin ṣe gbolohun... aṣọ, ki o si ma yọ ara rẹ lẹnu ara... Wa jẹun iṣẹ ọwọ rẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Ninu

ọsẹ yi wa ri pe awọn enia kan ... mọ riri rẹ. Ki o ni igbagbọ wipe gbogbo nkan a yọri si rere fun ọ... Mu ọkan kuro ninu aniyan ti k... ni fa nkan rere jade.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Aako...

rẹ lo wa ninu ọsẹ yi nitoripe wi... ni isimi ati ifaya-balẹ ọkan. M... jẹki ero buruku gba ẹ lọkan.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Awọn

ọrẹ rẹ kan a ba ẹni alejo; ara ... ni oogun ọrọ, ki o tọju ara rẹ. K... o maṣe jafara lati de ọdọ awọn ọrẹ rẹ atijọ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22)

Ṣọra nitori ijamba, aye lati ... so'de wa fun ọ; maṣe foya tara... wa ba oju rere enia pade.

CAPRISCORN (Dec 23-Jan 12...

Maṣe binu aburadi, ki o si ṣọra ... o ba nlo nkan ti o lewu ati wip... ki o mọ ṣe ere-gele ki o ba m... f'arapa.

# Eko Akete ILE OGBON (5)

( Lati owo Olalekan Onatade )

LEVER BROTHERS

NINU iwe itan mi ti ọsẹ keji ti mo kọ mo da orukọ diẹ ninu awọn Oyinbo onisowo ti awọn ara Eko nba lo ni ilu yi nigbana. Bi mo ti mba itan mi lọ ni ma tun ma da orukọ awọn ti mo ba tun nni-ran bi ọrọ ba ti nkan wọn.

Ni iwọn nkan bi ọdun marundinlogoji sẹhin ko si ẹniti o mọ awọn Oyinbo aladapo ti ẹ npe ni United Africa Company (UAC) li Eko. Awọn Oyinbo ti o jẹ baba'salẹ fun awọn oni-sowo nigbana ni Niger Company. Ibiti ile isẹ wọn wa nigbana ni Niger House ni Oke Olowogbowo di ọjọ oni.

Awọn Oyinbo Niger Coy yi lo ni West African Soap Company, awọn Oyinbo ọlọsẹ ni Apapa nigbana, awọn na ni nwọn tun ni Lever Brothers.

Ni aiye atijọ awọn Oyinbo ti o ni Lever Brothers ṣe bẹ-bẹ fun wa nipa nkan anfani; nwọn ṣi ṣọbu kan fun wa ni Broad Street l'Eko nibiti awọn G. B. Ollivant nta typwriter nisisiyi. G. B.O. Techenical Section ni mo wi. A npe ṣọbu ti awọn Lever Bros si fun awa talaka ni Eko nigba na ni LEVER STORES, ṣọbu yi lo fẹ dabi Kingsway Stores ti ode oni nitoripe ko si ṣọbu kan ti a npe ni Kings-Stores rara nigba na.

LEVERHULME

Ninu ṣọbu Lever Stores ti mo fi ẹnu kan yi, ọja bẹrẹ lati kọbọ kan (Penny goods) nibẹ titi ti o fi de ṣile kan. Gbogbo awa ara Eko igbana ni a ma nlọ ra nkan mẹdẹn-mẹdẹn nibẹ. Enia ma nwọ pupọ nibẹ; awọn ọmọ ile-iwe ni o fẹ ka ni tabi awọn bale ile. Awọn ọmọ ti nwọn bari owo iya wọn gbe nile, ibẹ ni nwọn a gbe pari rẹ si.

Ni ọdun 1924 ọkan ninu awọn ti o ni iṣẹ Lever Brothers, Lord Leverhume wa yẹ iṣẹ wọn wo ni Nigeria. Ọkan rẹ balẹ pupọ pelu owo ti o ni lọwọ; o wo gbogbo wa ni ilẹ Nigeria tan, o si lọ ba Gomina Hugh Clifford ti o jẹ oloru ilẹ Nigeria nigbana, o ni on fẹ ki o ba awọn ara ilu on ni ilu Oyinbo sọ ki on ra gbogbo ilẹ wa lati Eko de ilu Hausa. O ni ko to awọn ẹbi on ra.

Ọlọla Lord Leverhume yi ko ri ile hoteli ti o gbayi tobẹ ni ilu Eko nigbana, inu ọkọ elefin ti o mu wa si ilu Eko ni o pe aṣeyẹ (dinner) ni alẹ ọjọ kan fun awọn gbajumọ ode ọjọ na, awọn bi Sir Kitoyi Ajasa, Hon. Olawọlu Moore, S. H. Pearse, Adeyẹmọ Alakija, Dokita C.C. Adeniyi-Jones ati awọn bẹẹbẹ.

ILE MILLER

Nwọn ni ẹniti o ba de ile Mila (Miller Bros) ti ko ba ba la, ori rẹ lo buru. Awọn Oyinbo onisowo yi ti a npẹ orukọ wọn ni Miller Brothers jẹ awọn onisowo kan ti awọn enia wa ti o mba wọn ṣe iṣe pẹ ko jẹ fi ṣe ere rara. Nwọn nṣe otitọ pupọ fun awọn ti nwọn mba wọn lo.

Awọn Oyinbo Miller Brothers yi lo mu awọn oni kẹkẹ cycle ti a npe ni Raleigh wọ ilu Nigeria di ọjọ oni. Bi nwọn ti nta aṣọ orisirisi ni wọn ra epo ati koko (cocoa). Owo iyebiye ni awọn si nko sode fun awọn enia wa lati lọ si igbe-riko lati lọ ra awọn ọja wọnyi.

Ile ibiti iṣẹ awọn Oyinbo Miller na wa lọjọ yen lọhun ni Marina (ti o kọju si Custom, ile ibode, lẹgbẹ Barclays Bank) ile wọn na si gun titi o de Balogun Street ati Broad St. nibiti ọlọpa nnawọ fun awọn oni mọto loni. Nwọn si ni ile ifi ọja pamọ si ja nrẹrẹ kakiri.

Awọn Oyinbo Miller Bros, ni o kọ tete ko ibusun onirin (iron bed) wọ ile yi, opọku ọyẹku ni ọ nwọn ti nta awọn ibusun wọnyi. Ti o ba de ile iṣowo wọn wa ri ibasun onirin (iron bed) o ni ọkẹ mẹta, ọkẹ mẹrin, titi ti o fi de oni ọkẹ marun (ṣile mẹdọgbọn).

COLONIAL BANK

Bi o ba ti kuro ni ile awọn Oyinbo Miller wa bọ si ile awọn Oyinbo London and Kano Trading Coy (L & K). Awọn Oyinbo yi Apapa ati Kano ni nwọn fi gbogbo ara wọn si nigbana, ile iṣẹ ti nwọn fi si Ẹhingbeti yẹn lati ma gba igo oti ti nwọn nta lọwọ awọn ti nwọn ta wọn si pẹlu a ti tun ta awọn miran ni nwọn fi ṣi ile na sibẹ.

Awọn Oyinbo yi ni o kọ da oti pipọn sile ni ilu Nigeria. Apapa ni nwọn si nṣe e. Ni Oke Oya, awọ ẹran malu ni nwọn nra nibẹ; ọdọ wọn si ni a ti nra oti lẹmọlẹdi ati soda water nigbana.

Awọn ile ifowo pamọsi (Bank) ti a npe ni Barclays Bank nisisiyi, Colonial Bank ni a npe wọn nigba yẹn, ṣugbọn ti a ba fẹ da apara, a ma npe orukọ wọn ni KOLOWOLỌWỌ BANK. O si pẹ ki nwọn to da iṣẹ a nfi owo pamọ wọn pọ mọ ti awọn Bank nla kan ti o wa ni ilu Oyinbo ti ẹka iṣẹ wọn wa kakiri gbogbo agbaiye ti a npe orukọ wọn ni Barclays Bank. Wa ri pe apeja orukọ wọn ni Dominion, Colonial & Overseas.

Ibi kanna ni ile awọn Bank na si wa di ọjọ oni ni Ẹhingbeti (Marina) niwaju Custom l'Eko. Ti o ba si ti kuro ni ile wọn, wa ta koro si ṣọbu awọn Oyinbo India; K. C. Chellaram and Sons

OYINBO INDIA

Awọn Oyinbo onisowo India yi Ọlọtọ ni t'on ọtọ ni ti wọn; awọn meji ni emi mọ nigbati mo nsọ itan rẹ yi. Ikinni ni K. Chellarams & Sons, ikeji ni J. T. Chatrai & Sons. Imọlẹ awọn onisowo Chellaram ni o tan pupọ ju nigban; awọn nkan ti awọn India yi si nta ni awọn ojulowo aṣọ ti o ba ilu oloru (tropical weather) mu. Aṣọ oni siliki ati awọn nkan ẹṣọ ti a fi ntun ile ṣe ni ọdọ wọn ni wa ti ri wọn ra.

Ile ṣọbu ti nwọn nlo nigbana kere diẹ, sugbọn ti o ba de ibẹ iwọ alara paapa wa mọ wipe o wọ ile ọla; gbogbo rẹ a si tutu bi eti odo, lọfinda a si ma ja kanmu-kanmu. Awọn Imale ilu Eko ti nwọn ba ri nkan jaje fẹran lati ma lọ si ile-itaja yi lati lọ ra nkan ti a nfi ṣe ẹṣọ si ile wọn. Ṣaṣa si ni awọn gbajumọ Eko ti yio sọ wipe awọn ko de ibẹ ra aṣọ tabi nkan miran nibẹ ri.

ELETI-OFE D'ARABA

ELETI--OFE

ANJUWON KO ŞE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28 Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 468 Phone 23370.

VOL XIV. No. 827. SATURDAY JULY 14,- JULY 20, 1962.

# O Dun Mo Gbogbo Wa

Awọn agbalagba ni ilẹ awa Yoruba ni nwọn nma sọ wipe bi egungun ẹni ba mọ ijo jo, ori atọkun a ma ya. Ọro ti a fẹ fi şe olori ọrọ awa Oniwe irohin Eleti-Ọfẹ lọsẹ yi ni ofin tuntun kan ti awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ni ilu awọn aladugbo wa ni ilẹ Ibo fẹ gbe sile nipa awọn Dokita Ijọba ti nwọn fẹ ti ile-iwosan (Govt. Hospital) şe ileitaja wọn, lati mọ pa owo s'apo, ti nwọn nlo ibi işẹ wọn lati wa owo ni ọna-kọna, awọn ti ko ni anu lori gbogbo awọn alaisan ti nwọn nwa sọdọ wọn lojojumọ fun itọju.

Ọrọ awọn dokita onişegun Ijọba yi kişe Ipinlẹ Ila Orun nikan ni nwọn gbe nhuwa buruku yi O kari aiye ni ọrọ wọn. Bi o ba lọ sile-iwosan (General Hospital) ijọba ni Eko wa ri wipe iwa buruku na peleke nibẹ.

Bi o ba ti de ibẹ ti o sọ ira aisan ti o nşe ọ fun nọọsi (nurse) ti o nşe aşoju dokita ti o ba wa lẹnu işẹ, wara-were ni yio ti sọ fun ọ wipe o yẹ ki o lọ ri dokita ni aşiri nile rẹ bi o ba nfẹ iwosan kiakia.

Ti o ba jẹ wipe dokita alawọ funfun ni o ba ba pade ni ki o mọ wipe o şe ori rere. Şugbọn awọn ọmọ iya wa ti o nwa ọla-ojọ ko kọ lati ran ẹ si ọrun apapandodo nitori ati ran gbogbo awọn ọmọ rẹ lọ si ilu Oyinbo. Nwọn gbagbe wipe işẹ alanu ni işẹ dokita ati pe ibukun Ọlọrun ni fun ni ni ọla ti ki si fi lala kun un.

Laipe yi ni a gbọ wipe ọkan ninu awọn obinrin ti o ntoju awọn aboyun ni ile - iwosan Adeọyọ ni Ibadan ni ọna kan ti o fi ngba owo - ẹhin lọwọ awọn aboyun yi. Bi o ko ba lọ ba nile, ki o si ra oogun lọwọ rẹ, ki o si tun da esu-adako fun un, ki o mọ daju wipe o ko ni f'oju kan dokita bi o ti wu ki o gbajumọ to.

Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ kan saara si awọn oşelu Ipinlẹ Ila Orun fun ofin ti nwọn fẹ şe na wipe ẹnikẹni ninu awọn dokita Ijọba ko gbọdọ şe işẹ apasa'po mọ. A si tun gba ni imọran ki awọn Ijọba Ipinlẹ yoku ati Ijọba Apapọşẹ l'Eko şe iru ofin bẹ fun awọn dokita ile-iwosan Ijọba kakiri.

Işẹ alanu ni işẹ oniwosan, ẹ jẹki a ma şe anu fun ara wa.

# Iwe Si Olotu

## ITAN EKO AKETE

Laipẹ yi ni mo lọ si ile-ikawe wa (Library) ni University College nibi lati lọ ka iwe, nibẹ ni mo ti ri iwe irohin nyin, Eleti-Ọfẹ a'i ibiti Ọgbẹni Ọnatade gbe bẹrẹsi sọ itan ilu Eko ati bi nwọn ti nşe nibẹ ni aiye atijọ.

Alagba, inu mi dun pupọ lati ka awọn itan na; şugbọn a dara pupọ ti ẹ ba le fi iwe Eleti Ọfẹ kun eyi ti ẹ nfi ranşẹ si wa. Ti ẹ ba le şe bẹ, awa ti a nka iwe Yoruba ninu awọn akẹkọ ninu ile iwe-giga yi a dun lati ra wọn fun ipamọ fun ọjọ ẹhinọla.

Ọpọlọpọ enia le mọ mọ riri itan Eko Akete Ile-Ọgbọn na ti ẹ ntẹ jade, şugbọn ni ẹhin ọla nwọn mbọ wa lati ma fi owo wa iwe ti ẹ tẹ si kiri.

Ju gbogbo rẹ lọ, a nfẹ itan orişirişi ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ na si.

Emi ni,
Adunọla
University College,
Ibadan.

## ILE IPADE NI ILU AWE

Ẹ gba mi laye lati kin Ọgbẹni Bọlarinwa lẹhin fun ọrọ ti o sọ sinu iwe irohin yin Eleti-Ọfẹ laipẹ yi ti o sọ wipe a nfẹ ile ipade (town hall) ni ilu Awẹ nitoripe oju ti la ju wipe ki a mọ fi ojojumọ pe si ita gba ngba bi ọrọ kiri.

Ọpọlọpọ wa ninu ọmọ Awẹ ni a mọ daju wipe ti a ba nfẹ ilọsiwaju fun ilu wa a ni lati sera ki a tọwọ bọ apo wa ki a na owo fun nkan ire ilu na.

A bẹ awọn agbalagba ati awọn oloye ilu wa ni Awẹ, ki nwọn şe paramu lati şe eto bi ao ti şe da owo fun kikọ ile ipade na.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
Ọmọ Awẹ
Ibadan.

OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ŞE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIŞOWO LE ŞE TI ỌJA LE FI MA TA

BI IŞU AKARA GBIGBONA.

POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—ỌFẸ

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Ona-Ofun

Mo sọ fun yin lọsẹ ti o kọja wipe ma fi eti yin kọ ọrọ ipade ti a se laipẹ yi ni ile ọrẹ mi, Oloye A. M. A. Akinloye ni ita Oje ni Ibadan. Ṣugbọn mo ri onisẹ kan lati ọdọ awọn janmọ wa na lati ile Oluyọle, o ni agbalagba ki ba igbo jẹ, ki njọwọ ki nma sẹ ba aiye jẹ nitoripe gbogbo nkan ti oju ba ri kọ ni ẹnu nsọ.

Mo gbọ, mo si gba ọrọ ọrẹ mi na( mo fi orukọ b'oo laṣiri) ti o ransẹ yi si mi. Ki a mọ purọ fun ara wa, awọn oṣelu kan wc ni ilu Ibadan ọna-ọfun ọna-ọrun (Bread and butter politics) ni gbogbo iwa a nsare sihin, a nsare sọhun ti nwọn nṣe kiri.

## Ona-Orun

Emi ko fẹ sọ itan Ibadan si inu iwe yi ni lọlọ yi nitoripe mo mọ itan awọn oṣelu Ibadan daradara, o bẹrẹ lati ori bale Shittu titi ti o fi de ori Olubadan Alẹṣhilọyẹ (baba eielubọ), ki ẹ ma tun sọ ti baba wa, Akinyele mọ (baba igbagbọ) baba olotitọ. Mo ba baba wa yi Olubadan Akinyele lo pupọ nigbati nwọn wa lori aga idajọ, on ati Ologbe adajọ Abọdẹrin ni Kotu Bẹrẹ.

Ni aiye igbana ṣẹkẹrẹ ati ilu-aro ni, a ma njo a si tun ma nkọrin bayi si:

Baba mbẹ nile:
Kirinjin ki;
Baba mbẹ nile,
Kirinjin ki:
Alao o gbaṣọ lo lọwọ ẹnikọkan,
Baba mbẹ nile,
Kirinjin ki,
Alẹshiloyẹ, yokọlu,
Ko wa tan bi?
Yọkọlu, Yọkọlu,
Ko wa tan bi?

## Ija-Igboro

Nigbati igba tun di ti awọn ọdọmọde bi Ologbe Adegoke Adelabu (Pẹnkẹlẹmẹsi) a ba wọn ṣee lode Ibadan. Mo fẹ ki ẹ mọ wipe ALAGBARA ni awọn ara Ibadan ati pe pẹlu ọrọ agbara ni nwọn fi tẹ ibẹ do. Loni ẹ ma ngbọ orukọ bayi ADELABU, ADISA, AKINLOYE, AGBAJE ati AKINLEWỌNDE ti yio tun dide lati lo Ibadan lẹ mọ, ẹ ko mọ layi'po fun wa lọjọ tọla.

Orukọ ma nro enia; mo mọ ọrẹ mi Oloye Augustus Akinloye daradara. Boya on ko mọ mi mọ, on kere si wa nigbati baba rẹ Ologbe ma nmu apo koko ninu mọto wa ta ni Alakoro l'Eko. Ko si ibiti o ma ndə si ju ọdọ egbọn mi lọ ni Ereko Lane ni oju gọta ti awọn obinrin nta aṣọ loni. Emi ni mo si nma se onjẹ fun wọn ti nwọn ba wa ta ọja na l'Eko ki nwọn to mu ọja koko (cocoa) olowo gọboyi lọ si ilu Oyinbo nijọsi.

## Ni Ti Ibadan

Mo ni ọna- ọfun ni ona-ọrun ( bread and butter politic ) ni gbogbo wa m b a k i r i nisisiyi. Augustus Akinloye, ẹniti o k'ọwe si mi lati Ibadan wipe ki nma se ja'rọ, orukọ ti awọn paapa npe Oloye Akinloye ni AMA AKINLOYE (ama-ọ,-Akinloye) ati Agbaje ati Adisa, irọ gbogbo ti nwọn ba fẹ ki nwọn ma pa fun wa, ara Ibadan mọ ibiti awọn ngba lọ.

## Odun Egun

Mo gbọ wipe ọrẹ mi, Mojidi Agbaje ti ko ṣi nile, ti Majẹkodunmi fi se ẹleha ọsan gangan ni ko jẹ ki awọn ara Ibadan roju se ọdun egungun lọdun ni. Bẹni ti ẹ ri ọmọ Salami Agbaje-gori-itẹ. Sugbọn boya o gbagbe wipe ọdun egungun kise ọdun Kayokayo ti Ọlọla Tafawa Balewa ti o ran Adekoye wa si Ibadan nṣe.

Tabi ẹ ko mọ wipe inu le bi igi ko ya lu omi; inu si le bi omi ki o gbe e lọ. Inu le bi egun Alapansọnpa tabi egun Ololu ki ko awọn alatori lọ ba Adekoye ọmọ Majẹkodunmi ni oke Agodi.

Mo tilẹ gbọ wipe nisisiyi Adekoye ọmọ Majẹkodunmi paapa ko tilẹ nfẹ gba enia ni alejo mọ on na ti mba wọn lo ede "Ibadan lo mọ, o ko mọ layipo". Boya o le gba mi laye ki nmu on lọ si ita Oje, Oke Bẹrẹ, Ita Bałẹ Olugbode, Oke Foko, Oke Oluokun, Ọja Ayeye, Idikan, Ọja'ba ati Isale Osi ki a lọ fi wọ Awo egbẹ Ibadan-lo-mọ na. Emi Ayiluka paapa ti wọ egbẹ na mo si ti jẹ oye nibẹ. Bi enia ko ba gbọn ninu, ki o tun gbọn lẹhin ko le mọ awọn nkan ti a nṣe ni ilu Ibadan nitoripe Ibadan ko jọ Eko.

## Baba Abiye

Lati igbati nwọn ti fi ọrẹ mi Oloye S. L. Edu ("SLEE") jẹ Ajẹlẹ awọn Abiyamọ (tabi Baba Iibye ni ki npe?) ni Ipinlẹ Iwọ Orun nkọ ti ni anfani lati kọwe ki i ku orire. Mo ri nibi oku kan ni Oke Olowogbowo sugbọn ọwọ di lati ṣe "barika rẹ" lori oye tuntun na

Mo ti mọ Oloye Edu yi tipẹ ni Olowogbowo lọdọ Ọgbẹni Taju Thomson, "TAT" (Opomulero Mọja-alẹkan). Nkan ti o tun dun mi ni ipa ọrọ rẹ ni igbati Oloye Edu yi ngbe ọmọ ọrẹ mi kan, Abudu Mọjeed Animashaun, ni iyawo ti nko le wa sibẹ. Ologbe Animashaun ki fi mi se're ti mo ba de ọdọ rẹ ni sọbu ọlọwọ (G. Gottschalk) ni Gbagi ati ti mo ba lọ si inu ile rẹ ni Idikan, on ati Ologbe contractor Agoro; ọmọlẹhin wọn ni mo jẹ lọjọ na lọhun.

## Iya Abiye Nko?

Boya Edu ko ti mọ wipe iṣẹ pataki ni lati jẹ Ajẹlẹ awọn aboyun ati abiyamọ ati pe ni ile iwosan (hospital) Adeọyọ obinrin Oyinbo alanu kan ti wa nibẹ ti npe ni IYA ABIYE (Mrs. Leeming) ati pe awọn Sisi-Abiye kan wa nibẹ ti nwọn npa owo-a-pa-s'apo a...i. Gbogbo egbogi ile-iwosan ni nwọn ko lọ si ile wọn lati fi se owo. Ẹniti ko ba fun wọn lowo lẹhin ko le ri dokita. Mo mbọ wa ... ọrọ awọn Sisi-Abiye ni igbamiran nitoripe Sisi-a-bana ni o ... a mọ pe wọn.

Jọwọ SLEE boya o le ba mi ri Ọgbẹni Ade Thani ni ibi iṣẹ awọn eleti-ọfẹ onirohin ilu (Information Service) lọna Ẹlẹyẹle ni Ibadan, ki o jọwọ ki o ba mi kii ti Oye tuntun Olori awọn eleti-ọfẹ ti nwọn ṣẹṣẹ gbe fun un laiye Adekoye. Boya mo le fẹ wa ki Dokita Majẹkodunmi na, mo fẹ ki Ade Thani f'ọna han mi.

O di gba!

# Eru Aiye Ma Mba Mi (4)

## (Lati owo J. Ola Wins)

AFI asinwin enia?ni eru aiye yi ko ni ba rara. Sugbọn eni ti ko bi se ẹgbẹ tabi je inawo kan pataki ri ko le mọ ohun ti ẹgbẹ ugba ni ọrọ aiye yi jẹ fun elomiran. Bi a wi titi ko ni gbọ, bi a fọfọfọ ko ni gba, a fi ti o ba di igbati o ba ja j loju ni yio to mọ wipe aiye ti awa yi pe meji.

Ati ti ẹniti o ni owo lọwọ ri ti aiye ti sọ di ẹdun arinlẹ. Bi nwọn ba ti ri owo diẹ lọwọ rẹ, o ti di burọda apapa-ndodo ati ọkunrin ati obinrin, t mọ'e tagbalagba ni niwọn yio mọ para enu ọna ilẹ rẹ Iwọ na yio wa di ẹgbọn nitori owo ọwọ rẹ.

Nwọn yio wa mọ pa itan bi ẹyiti nwa iṣẹ, a di wipe o ba babami tan ni idi iya ati bẹẹbẹ lọ. Gbogbo ọmọ ilu ni yio wa mọ pe ọ ni baba awọn ni gbogbo igba ti owo wa lọwọ rẹ; gbogbo nkan ti o ba wi bi abẹ ge. o ti di orisa wọn nwọn yio wa mọ'bọ ọ bi eni bọ orisa. Nwọn ko ni ọlọrun miran mọ a fi iwọ nikan.

Iwọ na yio wa mọ pa aṣẹ le wọn lori bi o ti nfẹ, paapa nwọn yio tun ọ binu wipe o t'lẹ ran awọn nisẹ daradara.

### AIYE AKAMỌRA

Bi adanwo ba de, awọn kanna ni yio si tun wipe awọn ki ise ọmọ iya rẹ mọ awọn ko tan rara o dun ni a de o si ti tan a lọ niyen. Ara mi aiye koju ba yi lọ o, ẹniti o ri aiye ti ko, saa ara iku ni o nya oluwarẹ

Ninu Bibeli ọgbẹ i kan wa nibẹ ti orukọ rẹ nje Jobu o ni owo o ni ọla dukia lọ ja-nrerẹ ati ọmọ bẹ nigbati idanwo de aiye ni ẹlẹsan ni o de nitoripe ọna eru ni o gba ko owo na jọ, nwọn tun nyọ suti ete si lara Sibẹsibẹ ọgbẹni yi ko fi eti si ti awọn elegan na, o si mba bi ọlọrun ti ran 1; asinwa-asinbọ gbogbo dukia tun pada di ilọpo meji meji nwọn ni o yẹ ki o ri bẹ kẹ se o ni inu re ni.

Bẹnani ọgbẹni kan ti ngba owo nla ni ibi iṣẹ, o si ni awọn ọrẹ mẹta ti ko ni iṣẹ lọwọ ọgbẹni yi ni o mbọ wọn o nra bata si wọn lẹsẹ o nra aṣọ si wọn lọrun ọrẹ wọn na ndun yungba bi agbayun. Inu kan ni wọn ni nkan ti e ba ba lẹnu ẹnikini ni ẹ ma ba lẹnu ẹnikeji bẹ na ni ẹnikẹta pẹlu. Se e̟ ọ wipe "olowo kan o otosi mefa olosi di meje" ọgbẹni yi ipa ni o fi nra aṣọ sọrun nitori awọn ọrẹ rẹ wọnyi.

### IṢẸ BỌ

Laipe ọkan inu awọn ọrẹ yi ri iṣẹ kan ṣe, inu gbogbo nwọn si dun si wọn mba ọrẹ wọn na lọ. Ko si ija, ko si ita, ẹnikan ko ti gbe ori soke si ẹnikan, apo kanna ni nwọn ti nna owo, aṣọ kanna ni nwọn si nda. Ẹnikẹta na tuẹ ri pẹlu. Bi "ori kan ba surwọn a ran igba" ni ọrọ wọn na wa da.

Ko pẹ pupọ ni iṣẹ bọ lọwọ eni akọkọ ti o ti nbọ wọn. Ọga ibi iṣẹ da awọn medogun duro ninu awọn osiṣẹ na. Ọgbẹni yi jẹ ọkan ninu awọn ti awọn ti nwọn da duro, Inu rẹ ko bajẹ rara, nitoripe o ti gbẹkẹle awọn ọrẹ rẹ. Bi o ti dele o ko ọrọ yi o ro fun wọn bi iṣu ti ṣe ku, ti a wa loko ti a ngbe wa sile ati bi ọbẹ tiẹ bẹ ti ase si ikoko ti o si jinna ati bẹbẹ lọ fun awọn ọrẹ rẹ. Nwọn baa daro pupọ, nwọn si ni ki o ti ọkan rẹ balẹ wipe bi ko ri iṣẹ fun ọdun marun gbako bi o ba ti si awọn ki o ma foya gbogbo ọrẹ rẹ ni awọn yio san fun un pada.

Inu rẹ dun pupọ, o ni on dupẹ lọwọ ori on ati lọwọ Iya on "Ọlọrun mi mo dupẹ. A ṣe nitotọ ọrẹ ki gbe? Yọtọmi ni mo wa. Nisisiyi o yẹ ki nma rọki, ki ma jaiye."

Bi o ti bọ sita ni awọn ọrẹ rẹ mejeji yi ti bẹrẹsi yin'mu sii ti nwọn si sọ wipe, aṣiwere, iya yio jẹ boto si ọ lara bi o ba gbẹkẹle wa.

(Ko ti pari)

---

## Ko Iwe Si Olotu, Eleti-Ofe Nipa Oro Ilu Nyin Ti O Ba Ndun O Lokan.

---



# NIGERIAN PORTS AUTHORITY

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such Scrap materials as the Authority may offer for disposal with the exception of any items which may be separately offered for sale during the period 1st July, 1962 to 31st December, 1962, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disp sal in the Lagos or Apapa area.

A copy of the tender form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, on payment of a deposit of £5 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The completed tender form should thereafter be returned to the Secretary in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP" so as to reach him not later than Friday, 20th July, 1962.

The deposit of £5 will not be refunded in any event to any tender, who, upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for and to remove the materials made available.

Tenderers are warned that scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials although it is expected that most of the materials will be ferrous.

During the six-month period indicated, the successful tenderer will be required to remove, at his own expense, whatever scrap is made available for sale (with the exception mentioned above) within 7 days of being notified to do so. He will also be required to make necessary arrangements at his expense for all such scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

BAYO KEHINDE,
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice No. 729

4th July, 1962.

Cancer Scare....

# Smokers Are Switching To Pipes In England

## TOBACCO FIRMS GAINING GROUND

(By Our London Correspondent)

More and more cigarrette smokers are now switching to pipe smoking, reports our Commercial Correspondent from London, as a result many Cigarette manufacturers are now replacing their stocks with tobaccos and superb cigars made from the stuffs.

SHARES of the ALFRED DUNHILL pipe and tobacco firm spurted 15s to a peak 145s yesterday on news that Chairman Mary Dunhill is puffing up the dividend by 1s. a share to 7s. 6d., and handing round one free share for every two now held.

This follows a £54,000 jump in profits to a record £416,000 for last year.

### SWING

Miss Dunhill told me last night: "The latest smoking and cancer scare has brought a big swing to pipe-smoking. Some shops say their sales have doubled."

Burning lower: Shares of Imperial Tobacco-the Players - Wills cigarette combine-down 1s. yesterday to 49s. 6d. Gallaher fell 6d. to 31s. 6d.

## 'No Room' For Religion On Soviet Soil

MOSCOW — According to Moscow Radio, there is "no room" for religious beliefs and practices in the programme set forth recently at the Congress of the Soviet Communist Party.

The broadcast, made recently on the Moscow Domestic Service, declared also that "from the very spirit of the (Communist) programme, there arises the necessity for improving and extending atheistic propaganda." The goal, said Moscow Radio, is "the complete and final overcoming of religious beliefs" in a Communist society.

# Queen Visits New Town

BERKSHIRE—Her Majesty Queen Elizabeth II accepting the invitation of one Mrs. Sylvia Petford to enter her home when Her Majesty visited Bracknell New Town, Berkshire, recently.

Bracknell, situated some 32 miles west of London, is one of several new towns which are being developed to ease the problems of congestion in the British capital. The town comprises three neighbourhood centres of pleasant residential areas, and two industrial areas to the east and west of the town centre in which all the manufacturing industries are located.

The project is designed to form a coherent whole, with facilities for progressive development to keep pace with population increases.



Here in this picture you see the Queen entering Mrs. Petford's home.

# Irohin Soki

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Ole A Gbe Wiri

Boya ẹ ti gbọ irohin awọn ọlọṣadana-dana kan ti nwọn lọ da awọn akọwe Banki ti nwọn ngbe owo lọ si ile ifowo-pamọ ti Sapẹlẹ lọsẹ ti o kọja yi, ṣugbọn mo ti ri iwe waya gba lati ọdọ awọn olofinttoo mi wipe, ọwọ awọn ọlọpa'nu ti tẹ diẹ ninu wọn ati obinrin kan.

Irohin ọrọ na lọ bayi wipe ninu nwọn nṣe wahala ao ṣẹ owo-titun, a ko ṣẹ owo-titun ni awọn Banki ri iwe gba lati Sapẹlẹ wipe ki nwọn tun fi ọpọlọpọ owo-tuntun ranṣẹ si awọn. Owo na ni nwọn ngbe lọ ki awọn ọlọṣa to de ọna de wọn, nwọn si ja ọkẹ mẹta pọnun (£60,000) gba lọwọ wọn.

Awọn ọlọpa mọ wipe bi ko ba si iku ile tode ko le pani, nitorina wọn nṣe iwadi lati le ri eyi ti o ku ninu owo ti nwọn ji yi na, ṣugbọn ọwọ wọn ti tẹ awọn enia metala kan, obinrin kan wa ninu wọn. Awọn ọlọpa ko gba idurọ awọn ọlọṣa na; nwọn si ti ri ẹgbawa pọnun gba ninu owo ti nwọn ji na

## Owo Ori

A gbọ irohin kan lati Ibadan wipe Dokita Adekoye Majẹkodunmi, alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni dandan ni owo ori; Ofin owo ori tuntun ti o ti wa nilẹ laiye ijọba Oloye Akintọla on ni lati gbe e jade nitoripe Ijọba Ipinlẹ na nfẹ owo lati lo fun ilọsiwaju ati anfani awọn ara ilu kakiri gbogbo Iwọ orun.

A gbọ wipe owo-ori ti awọn mẹkunnu a ma san a kuro ni pọunu kan, ṣile metadinlogun a bọ a di pọnun mẹta gbako.

## Oro Iwadi

Adajọ G. B. A. Cokẹr, ẹniti Dokita Moses Adekoyejọ Majẹkodunmi, Alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun yan ni Alaga lati ṣe iwadi awọn ẹgbẹ alaṣepọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti sun ọjọ iwadi na siwaju di ọjọ mẹwa loni, Monday, July 23.

## Ogun Speaks Out

AN executive memmber of the Action Group, Chief M. A. Ogun who was summoned by the Party to explain himself why he should not be disciplined for alleged subversive activities against the Party told our reporter last night that,

"In the present crisis, I have never disguised my sympathy for Chief Akintọla who, I am convinced, is just a victim of prejudice and conspiracy. I should, however, want to make it abundantly clear that I am not a member of Chief Akintọla's United People's Party nor have ever contemplated resigning from the A.G.

"In spite of the publicity heralding it up to the time of writing, I have not received any communication or summons from the party's headquarters asking me to explain or defend anything.

"But I want all concern to know that if the penalty for expressing honest disagreement with Chief Awolowo is expulsion from the party, I am prepared to take it, when it comes, calmly and without any regret."

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 3370; OLOTU: OLA. ONATADE, 15, Kosoko St., Lagos,

# A Gbe Mission De!

## Oti Aladun, Oje Osan

Ọti aladun kan ṣẹṣẹ de si ilu Nigeria ti orukọ rẹ njẹ MISSION, bi enia ba mu ọti yi, ọkan rẹ a tutu nẹsẹ, wa ri wipe awọn Oyinbo ti ni ọgbọn lati rọ oje ọsan-mimu sinu igo, ati pe ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn ti tọ ọti na wo mọ iyatọ ti o wa ninu rẹ pẹlu awọn ọti-aladun miran.

Ọti yi si ti di nkan ti awọn ara Eko nlo ni ibi aṣeyẹ ọjọ-ibi, ikomọjade tabi nibi igbeyawo. Irohin ọti-didun yi ti tan kakiri ilu Nigeria, nibikibi ni o si le ti ra nisisiyi. Bi awọn Oyinbo ti nmu ninu ile ati leti okun, bẹni awọn gbajumọ enia-dudu nfi ṣe faaji nibikibi.

FINEST FRUIT FLAVOURS




*Naturally Good!*

BOTTLING DIVISION
WEST AFRICAN INDUSTRIAL VENTURES LTD. BOX 581 LAGOS.